9 SEP 1974
31/8/74

Kongi Nap WK 4
20, 23, 38.

ASIKO Bks Wk 4
7, 24, 37, 49,

ROSS BKS Wk 4
14 & 15

Imọlẹ Owuro

Ẹsin Ọrọ Wa: "IMỌLẸ DE! OKUNKUN PARADA"

UNITY NAPS
For 3 sure draws in Wk 6 try to see The Manager Unity Pools House, E4/226, Gbelekale Ibadan.
See him with ₦5 before 2 p. m. on Saturday.
2, 9, 16, 20

Independent Paper VOL. XIII No 654 SATURDAY AUGUST 31 — FRIDAY SEPTEMBER 6, 1974 5K. (KỌBỌ MARUN)

# GAMBARI LU GAMBARI PA




AWỌN onijo ilẹ JAMAICA ni orişi mẹrin ni ẹ nwo ninu aworan stamps iranti ti ẹ nwo yi. Wo awọn aworan na daradara, iwọ yio si gbadun rẹ.

IROHIN lati Sapẹlẹ ni Ipinlẹ Ado-Ibinni fi ye wa pe awọn Gambari meji ti nwọn jẹ ọmọ baba kanna ti ja ija nla kan ninu eyi ti ọkan lu ekeji rẹ pa.

Irohin na sọ pe ọrọ kan l'o şe bi ọrọ laarin awọn gende meji na, eyi ti o fa ki nwọn maa sọ oko eebu si araa wọn; ati pe nigbati o şe ni nwọn nmu ina leti araa wọn, ni ijakadi ba bẹrẹ.

Ni afikun, irohin sọ pe nigbati ọwọ ẹnikan dun ẹnikeji rẹ ju, ni onitọhun ba ki olugbongbo kan mọlẹ, o si ko o bo ẹni ti nwọn dijọ nja na.

Siwaju si i, irohin sọ pe lojiji ni ọkunrin na ti nwọn ko olugborg'io bɔ şubululẹ ti o si daku rọngbọndan. Nihin ni nwọn ti sare gbe ọkunrin na ti nwọn pe ni Yesufu Imoru lọ sile iwosan Sapẹlẹ nibiti awọn oulşegun ti sọ fun awɐn ti o gbe e wa pe o ti ku!

Bayi, awọn Ọlọpa ilu Sapẹlẹ ti mu ẹni ti oun pelu Imoru dijọ ja, nwọn si ti bẹrẹ si i fi ọrọ wa a l'ẹnu wo.

# KASIM RE'LU ỌBA

ỌGBẸNI M. Ola Kasim ti işe Alakoso ile-işẹ "IBUKUN ORISUN IYE RECORD" ba ọkọ ofurufu fi ilẹ Naijiria silẹ lọ si ilẹ Geẹsi laipẹ yi.

Irohin fi ye wa pe Ọgbẹni Kasim lọ si ilu Ọba lati lọọ şe eto, ki o si tọwọbọ iwe adehun pẹlu awọn alako-

(Woju ewe kẹfa)

# Kini o dun to yi?

ILE — IŞẸ OGO OLUWA KIITAN TRADIGN STORES, ti gbe awo rẹkọọdu nla titun ti gbajumọ oşere nni FATAI OLOWONYỌ ati awọn oşere rẹ şẹşẹ şe jade, eyiti nọmba rẹ jẹ OKLP 17, VOL. 3.



FATAYI OLOWONYỌ
(Onijita Aramọnda)

Awo na pabambari, o le gongo. A gbọ ma le lọ ni orin inu awo titun na. Ti ilu ti nwọn lu ninu rẹ ni ki a sọ ni tabi Jita aramọnda ti Olowonyọ ta sinu rẹ ? "Ko dun l'odo" ni awo rẹkọodu yi, "ti o ba dele a di oyinmọmọ".

Bakanna ni awo rẹkodu OKLP 11 ati OKLP 13, VOL 1 - 2, ti ẹ ti mbeere rẹ ti wa bayi fun tita.

Koşeemani ni awọn awo wọnyi fun igbadun abẹle nigbagbogbo.

Ẹ le ri wọn ra ni ile - itaja rẹkọọdu l'adugbo nyin tabi l'ẹdọ Olupinja:

OGO - OLUWA KIITAN
TRADNIG STORES,
51, Railway Line
Odi - Olowo, Muşin
Tel, 46252
Tabi ni Ẹka wọnyi:
* 119, Herbert Macaulay St.
Ebute - Mẹtta.
* 2, Badejọ Street, Agege
Lagos State.

# Moto ejo pa alalupupu

NI igbonagbooru ni iku gbe gende 'kunrin kan lọ ni adugbo Apakee l'ọna Sabo si Taki ni igboro ilu Ogbomọşọ l'opin ọsẹ ti o kọja lọhun nigbati alupupu ti ọkunrin na ngun lọ fi ori gbari pẹlu ọkọ ejo aagannabo kan ti o duro si ẹgbẹ ọna nibẹ.

Arakunrin na Oloogbe Toyeşe Ọpalẹyẹ, ẹni nkan bi ọdun mẹrindinlọgbọn jẹ ọga kan ni ile işẹ Ogbin ati ohun alumọni inu ilẹ ẹka ibi ti nwọn ti ngba bode lori ẹran ni Ipinlẹ Iwọ - Oorun (Cattle control post) ni Sabo, Ogbomọşọ.

Gẹgẹ bi nwọn ti fi ye onirohin wa nibi işẹlẹ na, Oloogbe Ọpalẹyẹ ngun alupupu rẹ (Under 175) eyiti nọmba rẹ jẹ WC 4733 bọ lati ibişẹ rẹ nigbati o dede fi ori gba ori pẹlu ọkọ ejo na nọmba KN 3480 ti o duro si ẹgbẹ ọna nibẹ.

Nwọn ni lẹsẹkẹsẹ ni ẹjẹ sọ ti oloogbe na si nja ọwọ ja ẹsẹ bi awọn ahunşọ ninu agbara ẹjẹ ati ọwara ojo ti o nrọ; ni nkan bii deede agogo mọkanla alẹ ni nwọn sọ pe

(Woju ewe kẹfa)

## ATIORO OMO ATIALA

# Mase f'ara we won [8]

Ani e ma gbagbe o
Gbogbo janmaa wa:
Ohun ti o to
L'o ye k'a f'ara we,
Iwa t'o rosomu
L'o ye k'a fi se'wa hu
Gbogbo iwa pata
T'o ba je t'esubeleke
O ye k'a sora,
K'a ma hu 'ru 'e nigbakan
Nitori pe bi a ba fi
Ara we gunnugun
Ori eni le pa,
Bi a ba f'iwa jo aluko
Aso eni le re dodo
Bi a si f'iwa jo aparo
Pipon l'aso eni i pon,
Aso a pon rokiroki
Iwa a si pon lukuluku.
Beeni b'iwa ba baje,
Oju oniwa yio ri nkan
Eni e ba ri e man bi.

E tete mura giri
Ki e gba'wa na sonu
L'owo irun won.
Nitoripe:
Molomo kii mo l'oun nikan,
B'ara ile eni
Ba si nje kokoro
Ti a ko tete wi:
Ni'jo ti kokoro
Ba di ewu gudugbe
T'o nhun ni l'orun
Ti ko je ka rorun mumi
Ogun dandan nii mu ba ni
Kii sii je ka sun
Asunfonle'fori
Nibi awa ba wa.
Nje k'a ma wule salaye mo
E wo opo enia
Ti mbe l'ode oni
T'omo won ti ya boogo!
E wo opo obi
T'ibanuje omo re
Ti so d'alailera okan
Nibi t'o ti nlaana omo.
E wo 'ye eni t'o ti ku
Nibi t'o ti nronu omo!
E si wo 'ye obi
Ti wahala ti so d'opije
Nibi t'o ti nwahala kiri
Nitori omo!
Omo elomii buru
O tun nfa ibi wale!
Omiran ya opije
T'o tun nfa osi kun osi,
Omiran si lowo lowo
T'o fi nse isekuse,
A r'eni n'iwa atata
Ti egbe kiko so di
Eniakenia l'oju ode.
A si r'omo
T'o ye k'o tu baba ninu
T'o f'ibanuje pa
Baba re l'oorungangan




Nje gbogbo enia pata
Ti ngbo nasia yi
O d'owo onikaluku o
E ma safarawe ibi.
Bi a si ki o nilo
Ti o ko gbo rara
B'o ba yi o lowo
Ma se so pe
Enikan l'o se o
Enikan l'o fa 'bi ba o.
Enikan ko se o o
Iwo na l'o se 'raa re.
Ati iwo eni nla
T'oo ti dele aiye pe,
Ati iwo majesin
Ti o sese ndide-'le.
At'iwo obi
T'o nko omo je lehin re,
O d'owo onikaluku
E tun oran araa nyin se
E maa ronujinle
L'ori oran omo enia
Ki e too safarawe;
Bi e ba ri 'hun t'o buru
E mase fara we won;
Bi e si l'enia ewe
T'o ba fee ko iwakiwa,

Nje ki l'o fa 'ru eyi
T'o koja afarawe!
Afarawe buburu
Ti omo won se
L'o fa ibi ba won
Se, agutan ti mba aja rin
Yio je igbe, o daju
B'omo t'o nilaari
B'a mba omolangidi se
Yio f'ise j'omolangidi;
B'enia si dagba
Ti ko wo esin re l'ese
Ti o nwo esin elesin sare,
Nigba t'o ba ya
T'esin re ba je l'ese
Oun na yio subu tesintesin ni
Nitorina gbogbo enia pata
Ti ngbo nasia yi
Maa ronu ki o too
Se ohun gbogbo ;
Iwa t'o ba to ni o farawe,
Eyi ti ko ba to
Mase ba won ya sibe;
Bi o ba si r'egbe aito

Ma laju sile
Ki t'ayat'omo re
Maa ba won kiri.
Nitori b'o ba d'oran tan
Nwon ko nii je o rimu mi,
B'o ba yi won lowo tan
E o jo tan an ni
Iwo yio si pelu
Nibi e gbe nru
Ibanuje oran na kiri.
Lai soro titi mo,
Bi o ba ri 'ru enia
Ti ko ka'ru ikilo yi kun,
Dakun ma fara we won
Nitori bi o ba fara we won
O te tan ni mo so fun o.
OLOLA ATIORO

# Olatunji Yusuff jade l'aiye

NI owuro kutukutu ojo Eti ti ise ojo ketalelogun osu kejo odun yi ni Alagba Olatunji Yusuff ti adape oruko re nje Oloko-ode jade l'aiye lehin aisan kan ti o se e.

Eni nkan bi aadorun odun ni ise, o fi aya meji s'aiye lo ati omo meta pelu opolopo omoomo.

Awon omo re ni Ogbeni Rasidi Yusuff, Ogbeni Saka Olatunji Yusuff ti ise Alakoso ile ise AIYEDETISOLA ELECRICAL STORES, ati Iyaafin Falilatu Raufu.

Ni irole ojo na ni nwon sinku oloogbe na ni agbo ile Oloro ni Ita Biigbo, Ibadan gegebi ilana esin Islam.

Alhaji Abdul Salami Mudasiru ti ise Lemoomu Mosalasi ile Iyalode ati awon janmaa re l'o kirun si oku l'ara.

Opolopo enia nlanla l'okunrin, l'obinrin, l'onile, l'alejo ati awon molebi oku l'o pejupese sibe. Ara won ni Alhaji Sanmori, Lamidi Lajide, Salawu Alimi, Taiye Oyelami, Gbada Akinola, L.O. Taiwo, Alhaji Adedeji ati beebee lo.



OLOOGBE ALAGBA OLATUNJI YUSUFF.

# Alhaji Olore r'oke Okun

IROHIN ti o te wa lowo lati odo Akowe Ijo Bamidele ti nwon npe ni Zumuratu Muminu, Alhaji Abdul Ganiyi Badmos fi ye wa pe omo Ijo won kan Alhaji Abdul Rasidi Gbadamosi Olore ti adugbo Idi-Ikan nilu Ibadan ti lo si ilu Oyinbo fun itankale esin Islam.

Akowe Ijo na fi kun un pe ninu irinajo re na, yio de Germany, Italy ati ile Geesi nibiti o so pe yio ti se waasi ti yio si nipa nibi eto awon obinrin kan ti nwon yio ba leha ki o too pada si Naijiria.

Akowe Ijo na so pelu pe opolopo enia nlanla lo sin in lo si idiko ofurufu Ikeja lojo na ninu eniti omo Ijo won pojulo.

# Jovial Naps

NAP 7 13 43
**Perm** 1, 2, 6, 9, 43
If no 43 draws come for 3 sure draws in week 6.

M. O. Oketona
15, Oke Ola St
Apomu-Ikire
43xxbk


IWE IGBAELODE DARA PUPO

1. Iwe gbogbo Agbo Omode ati Agba 10k
2. Kurani esu marun Yoruba 55k Esu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (15k)
4. Zabura ati itumo (55k)
5. Zabura Yoruba (40k)
6. Iwe Aiye Akamara (50k)
Iwe Eniasoro (50k)
7. Adedewe (35k)
8. Iwosan Ajebidan Ogun enia dudu (N3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni nla (N1.50)
10. Kekere (30k)
11. Iwe Oogun iwosan (N1.5) Kekere (45k)
12. Itan Anabi ati Yisa (55k)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FIOWO ATI STAMP (5k) RANSE SI:

(1) Alufa Yisa Igbaelode N2/394a Odoye Adeoyo Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaelode, Mosalasi Idi-Isin St, Isale Koto P. O. Box 17 Ilorin.

# ... jẹ ki a gbadura (3)

LATI ỌWỌ WOLI S. I. OWOẸYẸ

"OLUWA ni Oluṣọ-agutan mi, emi ki yio ṣe alaini" -Orin Dafidi 23, 1.

Njẹ l'oni gbogbo awa ti Oluwa ṣọ ti ko si jẹ ki a di alaini, ani awa ti Oluwa ṣe ni olowo, Onipo, Olori ati Oniṣowo ti o ri ere jẹ gbogbo ni Oluwa npe lati dahun ibeere na pe: "Bawo ni o ṣe lo ipo rẹ si ?"

Nitoripe lati nkan bi ọdun mẹta sẹhin ni mo ti nkigbe pe gbogbo Olori aiye ati Olori Ijọ ninu aiye, ti mo si nketantan pe, "Idajọ Oluwa de tan bayi" Mo si ṣalaye pe bi idajọ ba de bayi, ohun ti yio maa ṣẹlẹ ni pe aṣiri ohun ikọkọ kan ko ni i bo mọ.

Ọpọ Olori ni yio maa huwa ọbaiyejẹ yala nipa igberaga tabi imutipara ati bẹẹbẹẹ lọ.

Bakanna ni mo nkigbe pe, ninu awọn iṣẹlẹ wọnyi, ọpọ awọn enia ti aiye ko ka si ni yio wulo; a si nsọ pe ile Ọlọrun ni idajọ yio ti bẹrẹ bi Onigbagbọ ko ba kiyesara.

Nitoripe ọpọ Olori Ijọ ni yio maa tsi iwa hu, ti aini igbẹkẹle ninu Ọlọrun yio si maa mu ọpọ enia ṣi ile ya, eyi ti yio si fi iya kun iya ọpọlọpọ.

Lai fa ọrọ gun, awọn ọrọ Ọlọrun wọnyi ti bẹrẹ si i ṣẹ si Orilẹ-ede wa nipa aini igbẹkẹle to ninu Ọlọrun ati afojudi.

Ọpọ iṣoro l'o ti kun Orilẹ-ede wa bayi. Ọpọ awọn ti nwọn si jẹ Olori fun awọn alaini ni nwọn nṣi iwa hu. Ọpọ Olori ijọ ti di ẹmi ti ki i gbe ile ọjọ keji nipa ẹṣẹ aikiyesara.

Mo si ti sọ fun ẹnyin enia aiye pe, Oluwa sọ pe, "Ẹnikẹni ki yio jare l'ọdọ Oun Oluwa" nitori pe ko si enia ti a ko ti i ṣe iwaasu ihinrere Jesu Kristi leti rẹ-awọn nkan wọnyi ni yio si jẹ ẹri fun olukuluku niwaju Oluwa Ọga Ogo.

Nitorina ẹnyin enia ti nka iwaasu yi, ẹ duro ṣinṣin ninu ifẹ Jesu Kristi; ẹ maa ṣe ifẹ Rẹ nigbagbogbo ki ẹ ma si ṣe bojuwẹhin. Ẹ si maa gbadura pẹlu gẹgẹbi Jesu Kristi Oluwa ti kọ wa pe "Baba wa ti mbẹ li ọrun, ki a bọwọ fun orukọ Rẹ, ki Ijọba Rẹ de" - Matteu 6, 9 -- 10.

Njẹ iwọ Olori Ijọ, Olori ilu, ati Olori aiye ti ẹ ti nsọ pe "Ijọba Ọlọrun ko le de", njẹ bi o ba waa de lakoko ti Ijọ, tabi ilu, tabi orilẹ-ede ba daru mọ ọ lọwọ, nibo ni iwọ yio gba? Ati pe, iru orukọ wo ni a o pe ọ gẹgẹbi Olori?

Iwọ ha nfẹ orukọ rere lati jẹ ni ipokipo ti Ẹlẹda ba to ọ si bi? Iwọ ha nfẹẹ ṣe aṣeyọri rere bi? Nitorina, ẹ maa beere eyi lọwọ Oluwa ninu adura nyin.

Nigbati ẹnyin ba nṣe eyi ni ẹnyin ni agbara ti iṣe ti Oluwa lọwọ, ẹnyin ki yio si ṣe alaini ohun rere ti ẹ mbeere lọwọ Rẹ.

Njẹ nigbati ẹnyin ba ti ri gba bayi lati ọdọ Oluwa, bawo ni ẹ o ti lo ipo nyin na si ? Iwọ ti o jẹ Olori Ijọ, ṣe o ko ni i fi ipo rẹ fọ Ijọ ? Iwọ Olori ilu ṣe o ko ni i fi ipo rẹ tu ilu ? Iwọ Olori orilẹ - ede, ṣe o ko ni i fi tirẹ ni alaini lara ?



WOLI S I. OWOẸYẸ
Oniwaasu naa.

Inu adanwo ni gbogbo aiye wa bayi. Bi aiye ba yege, awọn olori aiye ni akoko na yio gba niyi; bi aiye ba si ṣubu, gbogbo Olori aiye ti ko ba fi ti Oluwa ṣe yio ba aiye lọ pẹlu igbi omi idaamu iku gẹgẹ bi akoko NOA.

Ṣugbọn iwọ - ki baa ṣe ọlọrọ tabi alaini ti o ba yege, ti o wa ni ipo otitọ ati ododo yio gba idalare gẹgẹbi a ṣe yọ NOA kuro ninu idaamu iku ijiya ẹṣẹ nijọsi-Genesisi 6, 8. Ẹ jẹ ki a gbadura

ADURA

Oluwa, awa enia Orilẹ -ede yi di ọwọ Rẹ, jọwọ, ma ṣe gba fun eṣu lati pa wa run; ma si ṣe gba fun awọn Olori wa gbogbo lati huwa aitọ ki iṣubu Olori ma baa ko ijiya ba ẹgbẹẹgbẹrun enia l'orilẹ - ede wa.

Oluwa, emi ti mo nka iwe yi di ọwọ Rẹ, jọwọ ma ṣe jẹ ki ọta ibajẹ lo mi lati kọju ija si otitọ ati ododo Orilẹ-ede mi.

Oluwa, ọwọ, ma ṣe fi abaawọn eṣu si mi l'ara ki orukọ mi ma baa bajẹ. Jọwọ Oluwa jẹ ki ọrọ Rẹ maa gbe inu mi ki o si maa ṣe rere.

Oluwa, ma ṣe jẹ ki eṣu sọ ọrọ Rẹ di ohun ibẹru fun mi ki ng le maa wa ire awọn Ojiṣẹ Ọlọrun gbogbo ati lati fi ọkan imoore han IWỌ Oluwa pe, IWỌ ni OLUṢỌ AGUTAN mi ti mo fi wa l'aiye ti mo si fi wa l'aaye titi di oni.

Oluwa Baba wa ti mbẹ l'ọrun, jẹ ki nṣe ifẹ Rẹ li aiye gẹgẹ bi nwọn ti nṣe li Ọrun. Nigbati o ba di igbẹhin ọjọ aiye mi ki ng maṣe di ẹni itanu ni ile Re ikẹhin nibi ISINMI AIYERAIYE. Amin.

## Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

| | |
|---|---|
| 10,961 | Adedeji Ọnabule, Ijẹbu-Ode |
| 10,962 | Yẹkini Ganiyu Ogbomọṣọ |
| 10,963 | Ade Omisala, Ẹgbado |
| 10,964 | Oyetunde Makinde, Ibadan |
| 10,965 | G. A Ọlaiya, Ila--Ọrangun |
| 10,966 | Ismaila Salami, Ibadan |
| 10,967 | Oyebanji Ṣango Ọyọ |
| 10,968 | Tajudeen Adeyemi, Ibadan |
| 10,969 | Ọladunni Mustapha, Shagamu |
| 10,970 | Stephen Oyekunle, Ọyọ |
| 10,971 | Taiwo Ọladeji, Ibadan |
| 10,972 | A. O Faokunla, Ikogosi--Ekiti |
| 10,973 | Fatai Saidu, Kwara |
| 10,974 | Kọlawọle Adekọla, Iree |
| 10,975 | Karimu Gbadamọṣi, Ogbomọṣọ |
| 10,976 | Raimi Ajagbe Eko |
| 10,977 | Kọlawọle Abidoye, Iragbiji |
| 10,978 | Rasaki Ẹgbẹteyinbo, Ibadan |
| 10,979 | Lukumọnu Ọlaitan, Moloko |
| 10,980 | E. O. Odebo, Abẹokuta |
| 10,981 | Nureni Rabiu, Abẹokuta |
| 10,982 | Tajudeen Akinyọọla, Ẹdẹ |

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA
DI

**Omo Egbe Imole Owuro**

(Iwe idi ọmọ Ẹgbẹ)

Orukọ rẹ ______________

Adirẹsi rẹ: ______________

Ọmọ ilu ti o jẹ ______________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akọwe Ẹgbẹ)
P. M. B. 5230, Ibadan

## IWE ORO OLORUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkọọkan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kobo (50k) pere.

Awon Iwe na ni:

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JỌWỌ ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa. Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ,
Box 1206,
Ibadan.

# Adekunle gbayi nilu Oyinbo

IROHIN ti o tẹ wa lọwọ lati ilẹ Gẹẹsi fi ye wa pe gbajumọ oṣere juju ọmọ ilẹ Naijiria nni General Prince Adekunle ati awọn oṣere Western Brothers Band rẹ ti nwọn wa ninu irinajo ipolongo are juju ati aṣa Ibilẹ wa kaakiri ilẹ awọn Alawọfunfun bayi ti bẹrẹ sii gbayi nwọn si ngbẹyẹ ni ibigbogbo ti nwọn ti nṣere fun awọn enia ilẹ na.

Irohin fi kun un pe, eyẹ nlanla ti awọn ọmọ ilẹ Naijiria ni ilẹ Gẹẹsi fi ki wọn kuabọ galọla

Gbogbo ibiti ẹgbẹ alare Ọmọ-Ọba Adekunle ba ti nṣere ni o maa nkunfọfọ fun ogunlọgọ awọn enia dudu ati funfun ti nwọn waa gbadun are rẹ. Pupọ igbati o ba si pari ere ni awọn enia na yio suru bo o, ti nwọn yio si maa bọ ọ l'ọwọ pelu yiyombo rẹ fun ohun didun rẹ paapaa Jita aramọ-nda ti ọmọ bibi inu rẹ, Ọlọla Sina Adekunle (ọmọ ọdun mẹẹdogun) fi da wọn laraya eyiti o mu ki awọn enia maa ho yee pe: 'Gita boy"! "Gita boy"!!

Ni ibẹrẹ oṣu kẹfa ọdun yi ni Ọmọ-Ọba Adekunle ati awọn oṣere rẹ ba ọkọ ofurufu fi ilẹ Naijiria silẹ.

Nwọn ti ṣere ni ilu London, Manchester, Liverpool ni ilẹ Italy ki nwọn too lọ si ilẹ awọn Germany nibiti wọn wa bayi.

Irohin fi ye wa pe eyẹ alarinrin ti awọn Akẹkọ Ọmọ ilẹ Naijiria ni ilẹ na ṣe fun wọn jẹ iru eyiti nwọn ko ti iṣe iru rẹ fun oṣere ọmọ ilẹ Naijiria kan nibẹ ri, ni nwọn fi pade wọn ni ebute Ọkọ ofurufu olu ilu na O koyọyọ, o le gongo.

Ni ilẹ Naijiria ẹwẹ, ile-iṣẹ "IBUKUN ORISUN IYE RECORD" ti gbe awo rẹkọdu nla titun ti o ṣe fun eyẹ idagbere ti awọn enia ti nfẹ tirẹ ṣe fun un ki o too kuro nilẹ yi jade.

Awo rekọọdu nla na ni gbogbo t'ọmọde t'agba ni ilẹ yi fi nṣe orin kọ bayi, nitori ara ọtọ ni, o kọja sisọ, o pabambari, koṣe emani ni fun gbogbo olufẹ are juju.

Irinṣẹ igbalode (stereo) adungbọleti ni nwọn fi ṣe e. Awo yi ni ko tun ni i jẹ ki aayin Ọmọ-Ọba Adekunle yin awọn olufẹ are rẹ pupọ ju bi o ti yẹ lọ fun irinajo oloṣumẹfa rẹ ti o lọ yi. Nitori a gbọ pe o di ipari oṣu kẹsan ọdun yi ki o too pada si Naijiria.



GEN. PRINCE ADEKUNLE
(O ndan nkan wo n'ilu Ọba)

## Abajade

IWỌNYI ni orukọ awọn enia ti o ṣe daradara ninu Idanwo Bibeli ti o jade ninu Imọlẹ Owurọ 10:8:74:

MẸWẸẸWA

Awọn enia ti o gba mẹwẹẹwa ni-: Abraham Ayanwọla lati Ejigbo, Lydia Arinọla lati Ibadan, James Awotoye lati Ijara, Mrs. C. A. Belo lati Ibadan, S. A Abidogun lati Ogbomọṣọ. Confort Ọlaniyi lati Kaduna, John Alagbe lati Ogbomọṣọ:

Mrs E. O. Adeoye lati Ibadan, K. Adeolu lati Ebutemẹta, Dorcas Adeyẹmọ lati Ibadan, R. A. Ayanwale lati Ogbomọṣọ, Lean Ayọrinde lati Ibadan, Deborah Ọlayinka lati Ileṣa, Evan Olu Daniel lati Ibadan, J. T. Ogunrinu lati Ogbomọṣọ.

Kẹhinde Ogundipe lati Ẹdẹ, Amos Ọlalẹye lati Ilero, Moses Ojẹlade lati Ibadan, Adejumọ Ọlatunji lati Ogbomọṣọ, Joseph Ọlawuyi lati Jos, Ọlalere Ayinla lati Abẹokuta, I. O. Okedare lati Ebutemẹta ati Emman Abegunde lati Omu-Aran Kayọde Adeolu lati

## Idanwo Bibeli

Eko gba marun.

IDAHUN IBEERE

Iwọnyi ni itọkasi idahun awọn ibeere na.

1. Luku Ori 11 ẹsẹ 28
2. I Peteru Ori 4 ẹsẹ 11
3. Dafidi Ori 119 ẹsẹ 105

LATI ỌWỌ JOṢUA KARIMU KOBIOWU

4. Jona Ori 1 ẹsẹ 1-2
5. Amos Ori 8 ẹsẹ 11
6. Johanu Ori 3 ẹsẹ 34
7. Hosea Ori 1 ẹsẹ 1-2
8. Esekiẹli Ori 1 ẹsẹ 3
9. Jeremiah Ori 21 ẹsẹ 11
10. Heberu Ori 4 ẹsẹ 12

IDANWO TITUN

1. Nibo ni Habakuku ti sọ pe, Oluwa jade lọ fun igbala?
2. Nibo ni Habakuku ti sọ pe, Mo gbọ ohun Oluwa ẹru si ba mi?
3. Nibo ni Habakuku ti sọ pe, Agbetaga ki i sinmi?
4. Nibo ni Habakuku ti sọ pe, Egbe ni fun ẹni ti o ta ẹjẹ silẹ?
5. Nibo ni Habakuku ti sọ pe, Nwọn ko dajọ otitọ?
6. Nibo ni Habakuku ti sọ pe, Ẹ maṣe mu ọti li amupara?
7. Nibo ni Habakuku ti sọ pe, Oluwa fi ẹsẹ wọn mulẹ fun ibawi?
8. Nibo ni Habakuku ti sọ pe, Awọn ẹni buburn yi olododo ka?
9. Nibo ni Habakuku (Woju ewe karun)

# Mase fi ẹsin re ran iborișa lowo (2)

IWỌ Mnsulumi ti o nka waasi mi yi, ma ṣe gbagbe ikilọ na ti a nṣe fun ọ pe ki o maṣe fi ẹsin rẹ ran iborisa lọwọ.

ITAN

Gbọ itan kekere yi ki o si fi kọgbọn. Nigbati Ojiṣẹ Nla Mohammed (S. A. W. S) bẹrẹ iṣẹ Ọlọrun ni ilu baba rẹ ti iṣe Mẹka, awọn alaigbagbọ da gbogbo ete lati pa a l'ẹnu mọ nipa iṣẹ Ọlọrun Ọba rẹ.

Nwọn fi owo bẹ ẹ, nwọn ṣe ileri ipo fun un pe ki o ma jiṣẹ Ọlọsnn ti iṣe iwaasu ododo mọ, ko gba fun wọn.

LATI ỌWỌ ALUFAA MUDASIRU ALIYU

Lẹhinna, nwọn tun mu un lagbara, ko ṣe iṣe. Nigbana ni nwọn waa kesi i fun ajọṣepọ, ni Oluwa waa fi suratu kafiruna. O gba ọrọ awọn alaigbagbọ ti iṣe Suratu 109 aya 1-6 ti o ka bayi:

"Wipe, mo pe ẹnyin alaigbagbọ, emi ko si nii sin ẹsin ti ẹnyin nsin; ẹnyin ko sin ẹsin ti emi nsin, emi ki yio sin ẹsin ti ẹnyin nsin. Ẹsin tiyin ni tiyin, ẹsin t'emi ni t'emi". Eyiini ni ọrọ ti Ọlọrun sọ fun aṣiwaju wa Mohammed (S. A. W, S.) ninu Kurani Mimọ lati fi aala si ajọṣe wa nipa ẹsin.

Nitorina, ẹ maṣe maa lọọ wo awọn abọrisa nibi ibọrisa wọn, awọn ni o yẹ ki nwọn maa waa wo nyin. Ki iṣe nyin fa wọn mọra ki nwọn si di Musulumi. Ẹ jọwọ, ẹ maṣe fi ohun mimọ ti Ọlọrun fun nyin yi eeri.

Ẹ tun gbọ ọrọ ti Ojiṣẹ - Nla Mohammed (S. A. W. S.) sọ pe ẹnikẹni ti o ba ti nṣe bi awọn enia kan ba ti nṣe, o ti di araa wọn.

Ko tii ṣẹlẹ ri pe eegun wọ Mọṣalaṣi kirun, bẹẹ gẹgẹ ni ko le tọ si Alufaa ati Alhaji ati Musulumi daadaa ki o tun maa tẹle eegun kiri, ayafi awọn Imale ti ko mọ ohun ti nwọn nṣe ni nwọn ntẹle eegun kaakiri tabi ki o maa woran eegun.

Nitorina, ẹ maṣe nipa ninu ohunkohun ti ko ba ẹsin Islam mu; ẹ maṣe fi ẹsin yin ran ibọrișa lọwọ.

# Awako Iseyin fee kole f'Ero

ẸKA ẹgbẹ awakọ ti ipinlẹ Iwọ - Oorun ni ilu Isẹyin ti dawọle kikọ ile ero kan ti nwọn sọ pe yio na wọn to ẹgbẹẹdogun Naira (₦3,000)

Nibi ayẹyẹ ifilọlẹ eto ile ero na ni ilu Isẹyin laipẹ yi, Akọwe ẹka ẹgbẹ na, Ọgbẹni J. A. Ojẹwumi sọ idi pataki ti ẹgbẹ awakọ ilu Isẹyin fi fẹẹ kọ ile ero na, eyiti o jẹ pe bi o ba ṣeeṣe oun ni yio jẹ akọkọ iru rẹ ti yio wa ni agbegbe ẹkun Ọyọ.

Ọgbẹni Ojẹwumi ṣalaye pe ọpọlọpọ inira ti awọn ero, paapa awọn onisowo ati arinrin-ajo nri kọ awọn lominu pupọ nipa aisi ile ero ti awọn enia bẹẹ le sun nigbamiran ti ilẹ ba su tabi ti nwọn ko ba ri ọkọ lati tẹsiwaju ninu irinajo wọn.

Akọwe ẹgbẹ na fikun un pe nitorina ni ẹgbẹ oun ṣe gbimọran lati kọ iru ile ero bayi eyiti yio mu idẹra ba ẹnikẹni ti o ba rin irinajo wa si agbegbe ilu Isẹyin lọjọ iwaju.

Lẹhinna ni olori ẹgbẹ awakọ ti Ipinlẹ Iwọ-Oorun ati Akọwe agba fun ẹgbẹ na, Ọgbẹni Jimọ Amọo ati Oseni Ladipọ kesi awọn awakọ ni Ipinlẹ Iwọ - Oorun lati dẹkun awọn iwa aiṣedeede kan eyiti o sọ pe nwọn maa nhu ti o si maa nfa ijamba mọto nigbagbogbo.

IKILỌ

Awọn Olori ẹgbẹ awakọ na kesi gbogbo awakọ lati ranti bi iṣẹ awakọ ṣe jẹ iṣẹ pataki to nitoripe laisi awọn awakọ, ọpọlọpọ awọn enia nlanla bi Adajọ tabi Amofin - Oludasilẹ ile iṣẹ gbogbo ko le lọ sibi iṣẹ wọn gbogbo.

Nwọn waa rọ awọn awakọ lati fi opin si ere isakusa ati lati dẹkun ati maa mu ọti amupara l'ẹnu iṣẹ; ati pe ẹniti ẹgbẹ awakọ ba mu ti o dagunla si ikilọ na, nwọn yio fa iru enia bẹẹ le Ijọba lọwọ.

MỌTO ṢỌJA

Ṣaju eyi, Baba ẹgbẹ ẹka ẹgbẹ na ni ilu Isẹyin, Alhaji K. Owonikoko ti kesi Ijọba Ologun Apapọ lati ṣeto lati ri i pe awọn ọkọ ti awọn Ọmọ Ogun ilẹ Naijiria ni iwe ofin ti ile iṣẹ afara - di - ofo (Insurance) nitoripe aini iru iwe aṣẹ irinna yi njẹ ki awọn awakọ Ọmọ Ogun wa ọkọ niwakuwa, eyiti nwọn sọ pe o nfa ọpọlọpọ adanu ba awọn enia.

Diẹ ninu awọn enia ti o wa sibi ayẹyẹ na ni: Oelfade, Jimọ Amọo, Oseni Ladipọ, Salami Taylor ati aṣoju orisirisi ẹgbẹ ni ilu Isẹyin.


## Olorireo

TOYIN POOLS HOUSE, Takie garrage, Ogbomọṣọ pe gbogbo awọn olorire lati wa fun atamotase ayo ni ọsẹ 5, 9, 15 ati 21.

Bi o ba fẹẹ ṣorire, darapọ pẹlu ogunlọgọ awọn ti o ti ṣe orire lati ọdọ wa ki iwọ na si di olorire. Ma jafara, wa l'oni.

Gbensoye Akano,
Box 66,
Ogbomọṣọ



## ORIRE FUN ARANSỌTA

A fi eyi kede fun gbogbo awọn Aranṣọ (Tailors) jakejado Orilẹ-ede yi pe, a ni ẹrọ ti o nṣe bọtini alaṣọ pẹlu oruka goolu leti rẹ (Dies mouls and Gold ring mouls) ni orisirisi fun tita bayi.

Bakanna ni a tun nta ẹrọ ti nfagi ti o si nlagi.

Ẹ maa bọ taara ni:-

G. ADEWALE & SONS (NIG.) LTD.,
5, GEORGE STREET,
ṢOMOLU VIA APATA,
LAGOS STATE.



Tabi ni:-

*26, NEW - COURT ROAD
IBADAN

Tabi ni:

*65, FOLAGBADE ST., IJEBU--ODE

Tabi ni:

*14, IGBIN ST., WARRI
MID--WEST.


## Kani-suru Pools Naps

STAR NAP, Nos:- "6 9, 45".

Target Pairs:- 6 & 7 must, 16 & 11 must, 44 & 45 must.

## Idanwo Bibeli

(Lati oju ewe kẹrin)

ti sọ pe, Oluwo mbẹ ninu Tempili Rẹ mimọ ?

10. Nibo ni Habakuku ti sọ pe, Olododo yio wa nipa igbagbọ ?

Ẹ tete fi idahun nyin pẹlu titọkasi Bibeli ṣọwọ si :

Joṣua K obiowu
(Onidanwo Bibeli)
Mapo Christ Church
Box 3062
Ibadan

# IWE SI OLOTU

## E ku alejo

Olootu,

MO ki nyin ku alejo ibẹwo Elejigbo Ejigbo Alaiyeluwa Ọmọwọnuọla Oyesọsin Keji ti o bẹ ile iṣẹ nyin wo gẹgẹ bi a ti ka a l'ọsẹ t'o kọja.

Ibẹwo na fi han pe awọn ọlọgbọn ati onimọ enia nkiyesi iṣẹ nyin, nwọn si nifẹ si i pẹlu. Adura mi ni pe ki Ọlọrun ki o maa ran nyin lọwọ, Amin.

Emi ni,

Adukẹ Adeyẹye
Abẹokuta

## Ori Owoeye pe

Olootu,

GBA ni l'aye lati kan saara si Woli S. I. Owoẹyẹ fun iwassu akọtun rẹ nigbagbogbo, imọran rere rẹ ati onjẹ iyẹ ti o fi mbọ wa.

Ti asọdun kọ, ko si ohunkohun ti o maa njade ninu iwe nyin ti ki i ni anfani tirẹ.

A ngbadura awọn eto nyin daradara o, Ọlọrun yio maa ran nyin lọwọ.

Emi ni,
Adio Ajewọle,
Ile—Ifẹ

## MURI GBEYAWO

Ni ọjọ Isinmi ti iṣe ọjọ kejidinlogbọn oṣu keje ọdun yi ni Igbakeji Akọwe Ẹgbẹ oni-mọto ti ilẹ Naijiria, Ọgbẹni Muritala Adewumi Salami gbe Omidan Oluyẹmisi Owolabi ni iyawo Ni ile Oluwo ni adugbo Mapo Ibadan ni nwọn ti ṣe inawo iyawo na, eyi ti o fakiki.

Diẹ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni Ẹgbẹ Ọlọkọ, Ẹgbẹ Awakọ, Ọgbẹni B. O Ladipọ, Y. O Belo, Yinna Ajibikẹ, Fatai Alabi, R. Ola City, Alfa Fatai Alagbe, Moses Alabi Ganiyu Amọo, Saka-Ọmọbọlaji, Ẹgbẹ Anifowose ti Ibadan, ati Muniru.


## ARA NFAAJO

MAGNATONE
BLOOD TONIC




MAGNATONE jẹ TỌNIKI atata - a tun ẹjẹ ṣe fun ọmọde ati agbalagba.

Beere ni ile itaja oogun ti o wa ni adugbo rẹ tabi ni:

BASOTO PHARMACY,
63, IDUMAGBO AVENUE
ITA AGARAWU
LAGOS.

# Kasim re'lu Ọba

(Lati oju ewe kini) so ile-iṣẹ Decca ni ilu London lati le ba wọn tẹ awo rẹkọdu titun ti gbajumọ oṣere Ọmọ Ọba Adekunle ṣe ati awọn oṣere rẹ ti nwọn wa ninu iriajo ipolongo are juju ati aṣa Ibilẹ wa ni orilẹ-ede na bayi, a gbọ pe lọhun ni awọn alare na ti kọrin na. Ṣugbọn a ko tii mọ igbati awo na yio jade.

Bakanna ni Alakoso na yio de ọpọlọpọ awọn ile-iṣẹ nlanla miran ti nwọn ṣe rẹkọdu lati le ni imọ si i fun ilosiwaju ati idagbasoke ile-iṣẹ rẹ.

Ọgbeni L. Akanji, ti iṣe Alamojuto Eto Oja (Sales Manager) ile-iṣẹ IBUKUN ORISUN IYE sọ fun onirohin wa ewe pe, ni aarin oṣu kesan ọdun yi ni Alakoso na yio pada si ilu Eko.

# Ijoba fofin de ero Meka

IJỌBA Ologun Apapọ ti fi ofin de aadọta enia ni ilẹ Naijiria pe nwọn ko tun gbọdọ rin irinajo kankan lọ si Mẹka ati Mẹdina mọ lailai.

Ikede Ijọba sọ pe ohun ti awọn enia na danwo nigba irinajo ti o kọja lọ ba ilẹ Naijirin l'orukọ jẹ pupọ.

Nwọn ni ara awọn iwa buburu ti nwọn hu na ni kiko oogun ti o lewu lọwọ, yiyi iwe owo irinna, yiyi iwe oniruuru gbogbo, ati fifi oniruuru orukọ aiyederu sinu iwe irinna gbogbo.

Nitori nkan wọnyi ni Ijọba Apapọ fi so o l'ofin pe lailai, awọn enia na ko gbọdọ lọ rin irinajo si Mẹka ati Mẹdina mọ nitoripe nwọn mba Naijiria l'orukọ jẹ.

Nigbana ni Ijọba kilọ fun olukuluku enia ti yio ba lọ si Haji l'ọdun yi lati ṣọra wọn gidigidi, bibẹẹ kọ, ofin yio lu eni ti o ba lu ofin.



ỌGAGUN AGBA YAKUBU GOWON

## Ali Madirasa Dilawati

NKESI gbogbo enyin ti ẹ fi orukọ silẹ si ile ẹkọ yi pe awọn ọmọ ile ẹkọ na yio wọle ni 7/9/74 ti iṣe ọjọ keje oṣu kẹsan ọdun yi.

Aaye wa fun iforukọsile ati fun ẹni ti o ba fẹẹ mu ọmọ rẹ wa. Ọfẹ ni ẹkọ yi fun ọdun kan; ẹ ma ṣe jẹ ki anfani yi fo nyin kọja.

Ile-ẹkọ na wa ni adugbo Olọrunṣogo ni oju ọna Ibadan si Akanran.

ALHAJI BELO ALI ADELANI
(ALAKOSO ILE-ẸKỌ)
E1/159 Ita Baalẹ Olugbode,
Ibadan.

## Apprentice Wanted

LEARN to become a successful printer. Learn on mordern marchine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary six & mordern III school leavers send them to learn the art of modern Printing, Marchine operating, and Book - binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/496 Yemetu Aladọrin,
Ibadan.

## Moto Ejo

(Lati Oju Ewe Kinni)

iṣẹlẹ na ṣẹlẹ.

Ọmọ ilu Oṣogbo ni nwọn pe Oloogbe na; awọn ọlọpa si nwadi iṣẹlẹ na lọwọ.



BAWO ni aworan ẹgbẹ yi ti ye ọ si? Aworan na jẹ ti agbaaragba ọkọ oju omi elepo kan ti awọn Gẹẹsi ṣẹṣẹ ṣe ti nwọn pe orukọ rẹ ni "Graythorp I". Ọkọ na ni nwọn pe ni eyi ti o tobi julọ iruu rẹ ninu aiye yi; ni ori agbami okun nla ti njẹ "Okun Ariwa" ni nwọn gbe ọkọ na si.

Ara awọn oṣiṣẹ inu ọkọ na ni ẹ nwo nni, Alaga ọran epo bẹntiroo fun Ijọba ilẹ Gẹẹsi Ọlọla Eric Drake ni o nrẹrin nni.

## Pools

### Ojo Adisa Naps

Hot (13&15) (2&1) (28&27)

Banka marun mbọ ni wks 8, 10, & 12. Fi N9 ranṣẹ fun tirẹ. Fun mẹtamẹta l'ọsẹ, fi N5 ranṣẹ si:

Ojo Adisa,
N4/273 Adeoyo
Oje Rd;
Ibadan

13, 2, 28 ?

### Sugar Naps

N4/273 Adeoyo
Ibadan.

Bank nos 12, 13, 18, 26, 27 & 30.

Pairs 37&38 44&45

NAP
27, 17, 5

# 20

Printed and Published by The Peoples Star Press Ltd, N4/496B Yemetu Aladorin P. M. B. 5230 Ibadan Olotu (Editor) Lawuyi Ogunniran